# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸLẸ

## ÌLÚ EÉRÚ

### Ìtàn ...

**Genesisi 19:1-29**

Abrahamu mọ̀ dájú pé arakunrin oun ti ṣe asiṣe nlá kan, ẹniti a npé ní Lọti nígbàtí o yan Sodomu fún awọn idile rẹ lati ma a gbé ibẹ̀. Awọn ìlú kereje kereje ni iṣàlẹ̀ Jordani rẹwà dáradára ti wọn si ni ohun ọ̀gbìn to pọ̀, ṣùgbọ́n àwọn pẹ̀lú kún fún ìwà ìbàjẹ́. "Awọn ọkunrin Sodomu ṣe ènìyàn búburú, àti ẹlẹ́ṣẹ̀ gidigidi niwaju OLUWA." Genesisi ẹ́é:ẹ́é. Ní igbẹhin, Ọlọrun pinnu lati pa àwọn ilu Sodomu ẹlẹ́ṣẹ̀ yi run nitori ìwà irira wọn, ṣùgbọ́n Ọlọrun kọ́kọ́ ran awọn angẹli meji sí Sodomu lati lọ gba Lọti la pẹlu awọn idile rẹ.

Kí awọn angẹli yìí tó wọ Sodomu, wọn dabi ẹniti nlọ si àjò. Nigbatí Lọti ri wọn ni ọwọ́ ìrọ̀lẹ́, tí o si ti mọ̀ pé awọn ènìyàn ìlú náà ki iṣe ènìyàn gidi, ti o si mọ̀ pé wọn le ṣe àwọn ènìyàn yi ni ibi lai mọ̀ wọn rí, o bẹ wọ́n ki wọn ba oun joko ni ọjọ́ náà ki wọn ki o le tẹsíwájú ni owurọ ọjọ́ keji. Awọn ọkunrin buburú ìlú náà ti nwò wọn, ki wọn tó dubulẹ, awọn ọkunrin ìlú Sodomu tọ Lọti wá, pé ki o mu awọn alejo rẹ jade si awọn ki awọn le e dá wọn mọ̀ lati ṣe ibi si wọn. Lọti bẹ̀ wọn títí ki wọn maṣe ṣe iru ohun ti wọn pinnu náà, ṣùgbọ́n wọn kò gbọ́ ti Lọti. Kàkà kí wọn gbọ́ ẹ̀bẹ̀ Lọti, ṣe ni wọn rọ́lu Lọti, wọn sì sunmọ̀ lati fọ́ ìlẹ̀kùn. Nigbàna ni awọn angẹli náà fa Lọti wọ ilé, wọn si bu ifọ́jú lu awọn ọkunrin náà ti wọn dúró si ẹnu ọ̀nà.



Ni òwúrọ̀ ọjọ́ keji, àwọn angẹli sọ fún Lọti ati àwọn ẹbi rẹ pé, "sá asalà fun ẹmí rẹ; máse wo ẹhin rẹ, bẹeni ki ìwọ ki o máse dúró ní gbogbo pẹtẹlẹ̀; sá asalà lọ si orí òkè, ki ìwọ ki o ma ba ṣègbé." Genesisi ẹ́ó:ẹ́í. "Nigba náà li OLUWA rọ̀jọ̀ sulfuru (okuta iná) ati iná lati ọ̀dọ̀ OLUWA lati ọrun wá sí orí Sodomu oun Gomorra." Genesisi ẹ́ó:ẹ̀è. Loti ati awọn ọmọbinrin rẹ meji ti wọn kò iti ni ọkọ ni wọn jade ninu ìlú, nitori iyàwó Loti bojuwo ẹhin, o si di ọwọ̀n iyọ̀. Ọ̀rọ̀ Ọlọrun sọ fun wa pé ni ìgbà ikẹhin, ipò gbogbo ayé yíò jọ ti Sodomu - bẹẹ gẹ́gẹ́ náà ni ìjìyà pẹlú!

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Ìlú meji wo ni a fi fun wa lati se àpẹẹrẹ iparun awọn ẹni buburú?
**2 Peteru 2:6**
Ti o sọ awọn ilu __________ oun __________ di eérú, nígbàti o fi ifọ́ afọ-bajẹ da wọn lẹbi ti o fi wọn ṣe apẹrẹ fun awọn ti yio jẹ alaiwa-bi-Ọlọrun.
Àkíyèsí: Ọlọrun pa awọn ìlú meji yi ru pẹlu iná àìnípẹ̀kun - Irú iná yi ni yio jó awọn ẹni buburu ni ọrun apadi.

2. Nigbawo ni a o pa awọn ẹni buburu run ninú iná ọrun apadi ?
**2 Peteru 2:9**
Oluwa mọ̀ bi aa ti iyọ awọn ẹni ìwà-bi-Ọlọrun kúrò ninu idanwo ati bi a ti ipa awọn alaiṣootọ ti a nje niyà mọ de ọjọ́ __________.
**Johannu 12:48**
Ẹniti o ba kọ̀ mi, ti kò si gbà ọ̀rọ̀ mi, o ni ẹnikan ti nṣe idajọ rẹ; ọ̀rọ̀ ti mo ti sọ, oun náà ni yio ṣe idajọ rẹ̀ ni __________ ______.
**Matteu 13:40-42**
Nitori náà gẹ́gẹ́ bi a ti kó èpò jọ, ti a si fi iná sun wọn; bẹ́ẹ̀ni yio rí ni __________ __________, Ọmọ-eniyàn yio rán awọn angẹli rẹ, nwọn o si kó gbogbo ohun ti o mu-ni-kọsẹ̀ ni ijọba rẹ̀ kuro, ati awọn ti o ndẹṣẹ; Yio si sọ wọn sinu iná ileru: nibẹ li ẹkún oun ipahinkeke yio gbe wà.
Àkíyèsí: Ninu awọn àyọkà òkè yii, Bibeli n fi ye wa kedere pé, awọn ẹni buburu ni a o gbé sọ sinu iná ni ojọ́ idajọ ni opin ayé - ki iṣe ìgbà ti wọn ba kú. Èyi sọ fun wa gbangba pé, ko ti si ẹnikẹ́ni ni ọrun apadi lọ́wọ́lọ́wọ́ bayi. O tilẹ̀ dara wípé ẹnikẹni ko iti jìyà títí ọjọ́ idajọ yio fi pé. A o san èrè fun olukuluku tabi idalẹbi ni dídé Oluwa wa ni ẹkeji, ki ise ki o to de (Ifihan 22:12).

3. Nigbati o jẹ́ wípé awọn ẹni buburu ti wọn ti kú kò si ninu iná bayi, níbo ni wọn wà?
**Johannu 5:28,29**
Ki èyi ki o máṣe yà nyin li ẹnu; nitori pé wakati mbọ̀, ninu eyití gbogbo awọn ti o wà ni __________ ________ yio gbọ ohùn rẹ, Nwọn o si jade wá; awọn ti o ṣe rere, si ajinde ìyè; awọn ti o ṣe buburu, si ajinde ìdájọ́.
**Jobu 21:30,32**
Ènìyàn buburu ni a fi pamọ fun ọjọ iparun, a o si mu wọn jade li ọjọ ríru ibinu, Sibẹ a o si sin in li ọ̀nà __________, yio si ma ṣọ́ __________ òkú.
Àkíyèsí: Bibeli fi ye wa pé, awọn ẹni buburu ti wọn ti kú, ni a fi pamọ́ ninu ipò-òkú títí di ojọ́ ajinde ni opin ayé. Wọn yio gbọ́ ohùn Jesu ti yio ma pè wọn, wọn a si jade wa lati inú ipò-òkú, ki ise lati inu iná.

4. Kinni èrè ẹ̀ṣẹ̀ tàbí ìjìyà fun ẹ̀ṣẹ̀?
**Romu 6:23**
Nitori ______ ni èrè ẹ̀ṣẹ̀; ṣùgbọ́n ẹ̀bùn ọ̀fẹ́ Ọlọrun ni ìyè ti kò nipẹkun, ninu Kristi Jesu Oluwa wa.
Àkíyèsí: Ìjìyà fún ẹ̀ṣẹ̀ ni ìyà àìnípẹkun ninu iná ọrun apadi, idakeji rẹ ni - ikú. Gbogbo wa ni yio kú ikú akọ́kọ́ (Heberu 9:27), ṣùgbọ́n Bibeli wipe awọn ẹni buburu yio kú ni inú iná ọrun apadi ti iṣe iku keji (Ifihan 21:8). Nipasẹ ikú akọ́kọ́, a o jí gbogbo wa si ìdájọ́ tabi èrè; ṣùgbọ́n kò sí ajinde ninu ikú kejì. Ikú keji jẹ òpin. Ni afikún, ti o ba jẹ wípé ìjìyà fún ẹ̀ṣẹ̀ ni oró àìnípẹkun ninú iná ọrun apadi, a ṣe wípé Jesu kò san gbèsè kankan.

5. Kinni ohun meji ti ènìyàn ni ẹ̀tọ́ lati le yàn ninu rẹ ?
**Johannu 3:16**
Nítorí Ọlọrun fẹ́ aráyé tó bẹ́ẹ̀ gẹ́, ti o fi Ọmọ bíbí kan ṣoṣo funni, kí ẹnikẹni ti o ba gbà á gbọ́ má bà __________, ṣùgbọ́n kí o le ní __________ __________.
Àkíyèsí: Awọn ìmọ̀ tabi ìwoye ti o nwípé awọn ẹlẹ́ṣẹ̀ yio kọ́kọ́ duro nibi kan lẹhin ikú wọn lati se atunse ki wọn to de ọrun, kò sí ninú Bibeli. Bibeli fi ọ̀nà meji tí a ti lè yàn ọkan ninú wọn hàn wá - ìyè àìnípẹkun tàbí ikú ayérayé (Deuteronomi 30:15).

6. Kinni yíò sẹlẹ̀ sí awọn ẹni búburú ni inú iná ọrun apadi?
**Orin Dafidi 37:10,20**
Nitori pé nígbà díẹ̀, awọn ènìyàn búburú kí yio sí: nitootọ iwọ o fi ara balẹ̀ wo ipò rẹ, kì yio sì sí, ṣùgbọ́n awọn ènìyàn búburú yio __________, awọn ọta OLUWA yio dabi ẹwà oko-tútù: nwọn o run; èéfín ni nwọn o __________ sí.
**Malaki 4:1,3**
SA kíyè si i, ọjọ́ náà mbọ̀, ti yio ma ________ bi ________ ìleru: ati gbogbo awọn agbéraga, ati gbogbo awọn olùṣe búburú yio dabi àkékù koríko: ọjọ́ náà ti mbọ̀ yio si jo wọn run, li OLUWA àwọn ọmọ-ogun wí, tí ki yio fi kù gbòngbò tàbí ẹka fun wọn, Ẹnyin o sì tẹ awọn ènìyàn búburú mọ́lẹ̀: nitori nwọn o jásí eérú lábẹ́ àtẹlẹsẹ̀ nyin, li ọjọ́ náà tí èmi o dá, li OLUWA awọn ọmọ-ogun wí.
Àkíyèsí: Àwọn ènìyàn búburú ní ọrun apadi yio gòkè lọ bi èéfín. Eérú wọn nikan ni yio kù.

7. Nibo ni ọrun apadi yio wà?
**Ifihan 20:9**
Nwọn si gòkè lọ la ibú ______ já, nwọn sì yí ibùdó àwọn ènìyàn mímọ́ ká ati ilu àyànfẹ́ náà, iná si ti ọrun sọ̀kalẹ̀ wá, ó sì jó wọn run.
**2 Peteru 3:10**
Ṣùgbọ́n ọjọ́ Oluwa mbọ̀wá bi olè li òru, ninu èyí ti awọn ọrun yio kọjá lọ ti ariwo nlá, ati awọn ìmọ̀lẹ̀ ojú ọrun yio si ti inú oru gbígbóná gidigidi di yíyọ́, __________ ati àwọn iṣẹ́ ti o wà ninú rẹ̀ yio sì jóná luluu.
Àkíyèsí: Ọrun apadi yíò wà ninú ayé, nitori ti yio jẹ ayé ninu iná.

8. Ṣe èṣù ni yio jẹ́ alakoso iná ọrun apadi ?
**Ifihan 20:10**
A si wọ́ eṣu ti o tàn wọn jẹ lọ __________ adágún iná ati sulfuru, nibiti ẹranko ati woli èké nì gbé wà, a o si maa dá wọn lóró t'ọ̀sán-t'òru lai ati lailai.
Àkíyèsí: Rárá! Satani jìnà sí ipò alakoso iná ọrun apadi, a o gbé eṣu gan an ṣọ sinú iná. Iná náà yio si sọ esu di "eérú lori ilẹ̀ ayé," Ọlọrun pẹlu sọ nipa satani pé, "iwọ kì yio sì sí mọ́ lailai. "Esekieli 28:18,19.

9. Njẹ́ iná ọrun apadi yio fi ìgbà kankan kú?
**Isaiah 47:14**
Kíyè si i, nwọn o dabi ________ koríko: _______ yio jó wọn: nwọn kì yio gba ara wọn lọ́wọ́ agbára ọwọ́ iná; ẹyin iná kan ki yio si lati yá, tabi iná lati joko níwájú rẹ̀.

Àkíyèsí: Lẹhin ẹ̀ṣẹ̀, ẹlẹ́ṣẹ̀ ati ohun gbogbo to n bẹ lori ilẹ̀ ayé ni a o parun, iná náà yio sì kú. Iná yii kò ni maa jó títí lai. Kò le se e ṣe lati pa ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ kúrò nipaṣẹ̀ oró ayérayé ni ọrun apadi. Ìpinnu Ọlọrun ni lati mu ẹ̀ṣẹ̀ kúrò, ki o si pá á run, ki iṣe lati mu ẹ̀ṣẹ̀ wà títí lailai. Ìwé Ifihan 21:5 sọ wípé, "Kiyesi i, mo ṣọ ohun gbogbo di ọtun."

**10.** Njẹ́ ọkan ati ara ni a o parun ni ọrun apadi?
**Matteu 10:28**
Ẹ má fòyà awọn ẹniti ipa ara, ṣùgbọ́n ti nwọn ko le pa ọkàn: ṣùgbọ́n ẹ kúkú fòyà ẹniti o le pa ________ ati ________ run li ọrun apadi.

Àkíyèsí: Ọ̀pọ̀lọpọ̀ lo gbàgbọ́ pé ọkan ki ikú, ṣùgbọ́n ni ìgbà meji ni Ọlọrun sọ wípé, "ọkàn ti o bá ṣẹ̀, oun o kú." Esekieli 18:4,20. Nitori náà, ni ìbámu pẹlu Bibeli, awọn ẹni búburú ni a o parun ninu iná ọrun apadi - ati ọkàn ati ara wọn.

**11.** Nitori awọn wo ni a o se dáná ọrun apadi ?
**Matteu 25:41**
Nigbà náà ni yio sì wí fun awọn ti ọwọ́ òsì pé, Ẹ lọ kúrò lọ́dọ̀ mi, ẹnyin ẹni ègún, sinu iná ainipẹkun, ti a ti pèsè silẹ̀ fun _______ ati fun awọn angẹli rẹ̀.

Àkíyèsí: Ìdí tí a fi dáná náà ni lati fi pa eṣu run ati awọn angẹli rẹ̀ ati ẹ̀ṣẹ̀. Bi mi o ba kúrò ninú ààrùn ẹ̀ṣẹ̀, a ṣe wípé n o parun pẹ̀lú ẹ̀ṣẹ̀, nitori bi a ko ba pa ẹ̀ṣẹ̀ run, ẹ̀ṣẹ̀ yio tún tẹsíwájú lati ma a ba gbogbo ayé jẹ́.

**12.** Bawo ni Bibeli ṣe se apejuwe iparun awọn ẹni búburú ?
**Isaiah 28:21**
Nitori OLUWA yio dide bi ti òkè Perasimu, yio si binu gẹ́gẹ́ bi ti afonifoji Gibeoni, ki o ba le ṣe iṣẹ rẹ̀, iṣẹ àrà rẹ̀; yio si mu iṣe rẹ̀ ṣe, ________ ________ rẹ̀.

Àkíyèsí: Ọlọrun kò le pinnu lati pa awọn ti o fẹ́ràn run. "Oluwa kò ... fẹ ki ẹnikẹni ki o ṣegbé, bíkòṣe ki gbogbo eniyàn ki o wá si irònúpìwàdà." 2 Peteru 3:9. Ọlọrun ma nsọ lemọlemọ́ fun wọn pé, "Ẹ yipada kúrò ninu ọ̀nà búburú nyin; nitori kini ẹnyin o ṣe kú? Esekieli 33:11. Pipanirun jẹ́ ohun to jìnà réré si ọ̀nà Ọlọrun wa, nitori náà ni a fi pe iná ọrun apadi ni "àjèjì iṣe." Ọlọrun ko ṣẹ̀ ohunkohun kù ninu ipinnu Rẹ̀ lati gba ènìyàn là. Kí a to pa wọn run, gbogbo ẹni búburú gbọdọ̀ ti mọ̀ pé Ọlọrun ti ṣe aanu fun awọn, ṣùgbọ́n awọn ni kò gba a (Romu 14:11).

**13.** Èdè Bibeli yi "iná àjóòkú" ṣe ki iṣe wipe o ntọ́ka sí iná náà pé kì íkú?
**Matteu 3:12**
Ẹniti atẹ̀ rẹ̀ mbẹ li ọwọ́ rẹ̀, yio si gbá ilẹ̀ ipaka rẹ̀ mọ́ tótó, yio si kó alikama rẹ̀ sinu abà; ṣùgbọ́n iyàngbo ni yio fi ______ àjóòkú sun.

Àkíyèsí: Rárá! A kò leè pa iná àjóòkú. Bi o tilẹ̀ wù kí o rí, yio jó ohun gbogbo run, ki o tó kú. Bi apẹẹrẹ, ninu ìwé Jeremiah 17:27 kìlọ̀ fún wa pé bi awọn ènìyàn Ọlọrun kò bá jẹ́ olootọ, Oun yio dá iná ni Jerusalẹmu "tí kì yio kú." Ìwé mímọ́ si fi ye wa pé aṣọtẹlẹ yi ti di mímúṣẹ. "Wọn jó ilé Ọlọrun, wọn si wó odi Jerusalẹmu lulẹ̀, wọn sì tun fi iná jo gbogbo ààfin ti o wa ninu rẹ̀... Lati mu ọ̀rọ̀ Oluwa sẹ lati ẹnu Jeremiah." 2 Kronika 36:19,21. Iná náà ko ṣe é pa títí t'ó fi jó ohun gbogbo tán; lẹhin náà ní ó kú. Kò tún jó mọ́ loni, bi o tilẹ̀ ṣe wípé Bibeli pè é ní "iná àjóòkú."



**14.** Ṣe ki iṣe ohun tí gbólóhùn yi "iná àìnípẹ̀kun" túmọ̀ sí ni wípé "iná tí kò ni òpin" ?
**Juda 7**
Ani bi Sodomu ati Gomorra, ati awọn ilú agbegbe wọn, ti fi ara wọn fun àgbèrè iṣe bakan náà, ti nwọn si ntẹle ara ajeji lẹhin, awọn li a fi lelẹ̀ bi apẹrẹ, nwọn njìyà ______ ________.

Àkíyèsí: A gbọdọ̀ jẹ ki Bibeli ṣe alaye ara rẹ̀! A o ri dájú ninu ẹṣẹ yi pé Sodomu ati Gomorra ni a parun pẹlu iná ainipẹkun bi apẹẹrẹ ọrun apadi, ṣùgbọ́n awọn ilú náà kò jóná mọ́. Wọn ti di eérú (2 Peteru 2:6), èyí ti iná ayérayé ma nṣe. O jẹ ayérayé ninu èrè rẹ̀. ( Wo àkórí àfikún " Ọkunrin ọlọ̀rọ̀ ati Lasaru.")

**15.** Nígbàtí Ifihan 20:10 sọ wipé awọn ẹni búburú ni a o ma dá lóró "títí lailai," ṣe ohun to túmọ̀ sí kọ ni àkókò tí kò lópin?
**Jona 2:6**
Emi sọkalẹ̀ lọ si ìsàlẹ̀ awọn òkè nlá; ilẹ ayé pẹlu idenà rẹ̀ wà _____ mi ________ titi: ṣùgbọ́n iwọ ti mu ẹmi mi wá soke lati inu ibú wá, OLUWA Ọlọrun mi.

Àkíyèsí: Rárá! Jona wà ninu ẹja fún ọ̀sán mẹta ati oru mẹta (Jona 1:17), síbẹ̀, o wipé "títí laí." O damilójú pé, o rò wípé títí ayé ni oun yio fi wa ninu ẹja náà. Ni èdè Giriki bi a ṣe túmọ̀ "títí láí" ninu ìwé Ifihan 20:10 ni "aion," ninu èyí tí a tí rí "eon." O ma nṣọ fun wa pé akoko ìgbà náà kò dájú, ìgbà díẹ̀ ni tàbi títí láí. A lo ọ̀rọ̀ yi "títí láí" ní ìgbà mẹrindinlọ́gọ́ta (56) nínú Bibeli lati ṣe ìjúwe ohun tó ti parí. Ní ọ̀nà kan, "títí láí" ntọ́ka sí ìgbé-ayé ẹrú tòótọ́ (Eksodu 21:6), ni ibòmíràn "títí láí" túmọ̀ sí ìran mẹwa (Deuteronomi 23:3). Fún ènìyàn, "títí láí" sabà ma ntúmọ̀ sí "níwọn ìgbà ti ẹni náà bá sì wà láyé" (1 Samueli 1:22,28).

**16.** Lẹhìn ìgbà ti a ba ti pa ẹ̀ṣẹ̀ ati ẹlẹ́ṣẹ̀ run tán, kinni Jesu yio ṣe fún àwọn ènìyàn Rẹ̀?
**2 Peteru 3:13**
Ṣùgbọ́n gẹ́gẹ́ bi ileri rẹ̀, awa nreti awọn ọrun titun ati ______ ________, ninu eyiti ododo ngbé.
**Ifihan 21:4**
Ọlọrun yio si nu omijé gbogbo nù kúrò li ojú wọn; kì yio si si ikú mọ́, tabi ọ̀fọ̀, tabi ẹkún, ________ ki yio si ________ mọ́, nitori pé ohun atijọ ti kọja lọ.

Àkíyèsí: Ọlọrun yio kọ́ ayé titun ati ọrun titun lori eérú ayé yìí ti a ti wẹ̀ mọ́. Ọlọrun se ileri ayọ̀, àláafíà, ati ìdùnnú ti kò se e ròhìn tán fun gbogbo awọn ohun alaye ni ayérayé.

**17.** Ṣe iṣoro ẹ̀ṣẹ̀ yio tún padà wáyé?
**Nahumu 1:9**
Kili ẹnyin ngbiro si OLUWA? Oun o ṣe iparun de opin, ìpọnjú kì yio ________ lẹrinkeji.

Àkíyèsí: Rárá! Ilérí náà dájú. Ẹ̀ṣẹ̀ kò ní wáyé mọ́.
**Isaiah 65:17**
Sá wọ́ ó, emi o da ọrun titun ati ayé titun: a kì yio si ranti awọn ti isaaju, bẹ́ẹ̀ni nwọn kì yio wá si àyà.

**18.** Ìbéèrè tó lágbára wo ni Jobu bèèrè?
**Jobu 4:17**
Ẹni kíkú le jẹ́ olododo níwájú Ọlọrun, ènìyàn ha le ________ ju ẹlẹda rẹ̀ bí?



Àkíyèsí: Ṣé bí ọmọ rẹ̀ ba di ogbologbo apànìyàn, ṣe wà á wò pé o yẹ fún ìbàwí bí? Mo mọ̀ dájú pe, wà á bawí. Ṣùgbọ́n ṣe o le fẹ́ kí a jó ọmọ náà nínú iná láàyè, nínú ìrora nlá fún ọjọ́ kan péré? Dájúdájú, o ko ni gbà. O kò le e dúró lati wò ó. Bẹ́ẹ̀ pẹlu Ọlọrun onifẹ ko le dúró lati ma wo ọmọ rẹ̀ ninu oró. Ìyẹn gan yio burú ju ohun tó burú ju ògun lọ. Njẹ́ irú ẹni ti Ọlọrun jẹ́ ní èyí bí? Rárá, ka ma ri? Ìyà ọ̀run apadi yíò jẹ́ ohun ti Ọlọrun funrararẹ kò ní le e mú mọra àti wípé o ṣe lòdì sí ìwá ìfẹ́ àti ìdájọ́ Ọlọrun

# Èsì Rẹ

Ju ohun gbogbo lọ, Jesu fẹ́ ki o ba Oun gbé ninu ijọba ologo titun Rẹ̀, O fẹ́ kí o jogún ilé tí Oun ti lọ pèṣè silẹ̀ fun ọ. Ṣé o ṣetán bayi lati tẹ́wọ́ gba ẹ̀bùn tí Ó fẹ́ fún ọ?

ÌDÁHÙN: ______________

# Àfikún

Ipele yi yio fun wa ni awọn ìròhìn kíkún lati tún kẹkọ síwájú.

## Ọkunrin Ọlọ́rọ̀ ati Lasaru

Ọpọlọpọ ma nlo òwe yi lati ma a fi idi rẹ mulẹ̀ pé ni kété ti eniyàn ba kú ni yio lọ si ijọba ọrun tabi si ọrun apadi. Ki ise ohun ti Jesu nsọ ni èyí nígbàtí o sọ ìtàn yí. Ọ̀rọ̀ ti Jesu lò fun "ọrun apadi" ni "ipò òkú," ibi oró ti awọn Giriki mọ̀ pé ki ise otitọ́. Yio ti yé awọn Ju to ngbọ nigbati Jesu npa òwe yi, pe Jesu nlo ohun ti awọn eniyan ro wipe ibi oró ni lati ṣe alayé Rẹ̀ ni. Ti a ba wo Luku 16:19-31 dáradára, a o ri wipe òwe yi kún fun awọn àmì kan ti Jesu kò fẹ́ ki a tumọ̀ gẹ́gẹ́ bí Ó ti sọ ọ́.

- Bi i apẹẹrẹ, njẹ́ gbogbo awọn ti a gbàlà ni o nlọ si oókan-àyà Abrahamu bi? Rárá.
- Njẹ́ awọn ti wọn wa ni Ìjọba Ọlọrun ati ọ̀run apadi le e ba ara wọn sọ̀rọ̀ bí? Rárá.
- Njẹ́ èékán omi kan le è tu ẹni tó wà ninu oró iná ọrun apadi ni ahọ́n bí? Rárá.
- Njẹ́ Abrahamu lo mọ awọn ẹni tí a gbàlà ati awọn to ṣègbé ni? Rárá.

Ni ọ̀nà kanna, a kò le è lo òwe yi lati kọ́ ènìyàn pé àwọn to ba kú kí ó tó di ọjọ́ ìdájọ́ ikẹhin ti òpin ayé, wọn o lọ sí ìjọba ọrun tàbí ọrun apadi. Johannu 12:48 sọ wípé, "ọ̀rọ̀ ti mo ti sọ, oun naa ni yio ṣe idajọ́ rẹ̀ ni gbẹhin ọjọ́."

Ki wa ni òwe yi túmọ̀ sí? Ọkunrin ọlọ̀rọ̀ yi ntọ́ka sí orilẹ̀-èdè àwọn Ju, ti wọn nṣe ajọyọ̀ lori iwé mímọ́, ti alágbe lẹnu ọ̀nà jẹ́ - keferi - ti ebi npa fún Ọ̀rọ̀. Jesu pari òwe náà pẹlu ìwòye pé "Bi nwọn kò bá gbọ́ ti Mose ati ti àwọn woli, a kì yio yi wọn li ọkàn pada bi ẹnikan tilẹ̀ ti inú okú dìde." Luku 16:31. Ni tootọ, Jesu tún ji okú ẹnikan dìde ti a npè ni Lasaru, púpọ̀ ninu awọn olórí àwọn Ju kò tún gbàgbọ́ sibẹ̀ (Johannu 12:9-11).

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678

YOR-SP10.indd 2 12/7/12 8:59 AM